Language: Yorùbá

# Èrò nípa Akọni Gbére Ajẹmóṣèlú nínú Orin Ìdárò Yorùbá

**Paul Akíntúndé AKÍNWÙMÍ (Ph.D)**
Department of Linguistics and African Languages
Obafemi Awolowo University, Ile-Ife. Nigeria.
E-mail: aakinwumi@oauife.edu.ng
ORCID iD https://orcid.org/0009-0002-5156-6162

**ÀṢAMỌ̀**
Ìlépa iṣẹ́ yìí ni láti ṣe àwárí àwọn àṣàyàn akọni inú ètò ìṣèlú tí ọ̀rọ̀ nípa wọn jáde nínú orin Yorùbá lẹ́yìn ìgbà tí wọ́n kú tán, kí a ṣe àfàyọ ohun tí ó sọ wọ́n di akọni, kí á ṣe àfihàn èrò ọ̀kọrin nípa wọn. Iṣẹ́ yìí ṣe àṣàyàn àwọn ọ̀kọrin ìgbàlódé ní àwùjọ Yorùbá, ó sì ṣe àfàyọ àwọn ipa akọni tí ó ti kú gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú orin ìdárò tí wọ́n kọ fún wọn. Ìdí tí ó fi jẹ́ pé àwon ọ̀kọ̀rin ìgbàlóde ni a ṣà yàn ní pé àwọn akọni ìgbàlódé nínú ètò ìṣèlú náà ni ó jẹ iṣẹ́ yìí lógún. Ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí wáyé ní ìlànà tíọ́rì Ìmọ̀-Ìtàn. Ọ̀nà mẹ́ta ni a lè pín àwọn akọni gbére ìdí ìṣèlú tí wọ́n ti kú wọ̀nyí sí nípa wíwo irúfẹ́ ètò ìṣèjọba tí wọ́n ṣe – akọni ètò ìṣèlú ìbílẹ̀, nínú ètò ìṣèlú àwaarawa àti akọni ètò ìṣèlú ìjọba ológun. Lára àwọn kókó-èrò tí ó jẹ mọ́ akọni gbére tí iṣẹ́ yìí ṣe àfàyọ ni ìdárò ikú akọni, ìtọ́kasí irúfẹ́ ikú tí ó pa wọ́n, ìtọ́kásí ẹni tí ó kú gẹ́gẹ́ bí ènìyàn ńlá, ipò tí òkú dì mú nígbà tí ó wà láyé àti bẹbẹ tí ó gbé ṣe lórí ipò náà. Iṣẹ́ yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé bí ènìyàn bá ṣe rere gẹ́gẹ́ bí akínkanjú tàbí fi ìfẹ́, àìmọtara-ẹni-nìkan àti ìgboyà jà fita-fita láti yọ ìlú àti àwọn ìran rẹ̀ kúrò nínú ìsìnrú àti làásìgbò nígbà tí ó wà láyé, bí irú onítọ̀hún bá kú tán, ayé ó sì máa polongo rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí akọni, ìpolongo wọn yìí yóò máa jẹ yọ nínú orin tí àwọn ọ̀kọrin bá ń kọ àti ìhà tí àwùjọ bá kọ sí wọn. Èyí ni yóò sì jẹ́ kí a lè tọ́ka sí irúfẹ́ àwọn akọni bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ bí akọni gbére.

**KÓKÓ-ỌRỌ̀**
Akọni, Akọni Gbére, Orin Ìdárò, Ìṣèlú, Òṣèlú, Yorùbá

## Reflexões sobre o herói político Gbére nas Lamentações Yorubá

**RESUMO**
O objetivo deste trabalho é identificar determinados heróis políticos mencionados em canções iorubás após suas mortes, identificar o que os tornou heróis e revelar as reflexões dos poetas a respeito deles. O estudo selecionou poetas contemporâneos da sociedade iorubá e identificou os papéis desempenhados pelos heróis falecidos, conforme retratados nas elegias a eles dedicadas. A escolha de poetas contemporâneos justifica-se pelo interesse deste trabalho nos heróis do sistema político atual. A análise baseia-se nos princípios da Teoria Histórica. Esses heróis políticos falecidos podem ser classificados em três categorias, de acordo com o tipo de governo que serviram: heróis do sistema político tradicional, heróis do sistema político militar e heróis do governo militar. Entre os temas relacionados aos heróis do passado explorados neste trabalho, destacam-se o lamento pela morte do herói, a referência às circunstâncias de seu falecimento, a exaltação da grandeza da pessoa falecida, o cargo que ocupava em vida e suas ações nesse posto. O trabalho estabelece que, quando um indivíduo pratica o

bem como herói ou luta — com amor, altruísmo e coragem — para libertar seu país e seus descendentes da escravidão e da pobreza durante sua vida, o mundo o reconhece como herói após sua morte; esse reconhecimento reflete-se tanto nas canções entoadas pelos cantores quanto na atitude do público em relação a eles. Isso nos permite classificar tais figuras como heróis exemplares.

**PALAVRAS-CHAVE**
Herói, Herói mundial, Canto de lamento, Política, Iorubá

**The Concept of Political Life-Heroes in Yorùbá Elegiac Songs**

**ABSTRACT**
The focus of the paper is to dig out some political heroes whose issues preoccupied Yorùbá songs after their death, to identify what made them heroes and to show the singers' perception about them. This work selected some Yorùbá contemporary singers and elucidated the concept of dead political heroes as it is portrayed in the elegaic songs composed for them after their death. The reason for the selection of these comtemporary singers is because this paper focuses mainly on comtemporary political heroes. The theory used for the analysis of this paper is Historicism. It shows that the political life-heroes that have died can be categorised into three by examining the system of government they served: traditional political life-heroes, civilian political life-heroes and military political life-heroes. The life-heroes related themes identified in the work are lamentation of the death, reference to the causes of the death, reference to the dead as public figure, the position of the dead while alive and his/her roles while holding the position. This work shows that if a person does what is good as a hero/heroine or fought shelflessly and courageously to saẹe his town and people from unrest and slavery/captivity while alive, people will continue to proclaim his/her name after the death. The proclamation of his/her name will preoccupy the songs composed by singers to mourn his/her death and the attitude of the society towards the songs. Therefore, such hero can be referred to as a life-hero.

**KEYWORDS**
Hero, Life-Hero, Historicism, Elegiac songs, Politics, Yorùbá

**Ìfáárà**

Èrò ìjìnlẹ̀ àwọn Yorùbá nípa pé ọjọ́ a kú là á dère, èniyàn kì í ṣunwọ̀n láàyè ṣe àfihàn ojú àmúwayé àwọn Yorùbá nípa pé èniyàn máa ń gba iyì lẹ́yìn tí ó bá kú ju ìgbà tí ó wà láyé lọ. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé nígbà tí ẹlòmíràn bá kú tán ni ayé tó máa ń mọ irú ẹni bẹ́ẹ̀ sí akọni. Lọ́nà mìíràn, bí wọ́n bá mọ èniyàn ní akọni nígbà tí ó wà láyé, bí onítọ̀hún bá kú tán, ayé lè má gbọ ohun kankan nípa rẹ̀. Èyí ni pé ó bá orúkọ kú. Àwọn akọni gbére ni àwọn tí ayé mọ̀ ní akọni nígbà tí wọ́n wà láyé, tí òkìkí wọn kò sì tún parun nígbà tí wọn bá kú tan tàbí akọni tí ó farasin nígbà tí ó wà láyé, ṣùgbọ́n tí òkìkì rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí akọni bú yọ lẹ́yìn ikú rẹ̀. Lárà ohun tí ó máa ń fi ìdí akọni múlẹ̀ lẹ́yìn ikú rẹ̀ ni ìhà tí àwọn ọ̀kọrin bá kọ sí akọni. Àkọtúnkọ orin jẹ́ ọ̀kan lára ohun tí ó máa ń fi hàn pé akọni gbére ni ẹnìkan. Bí èniyàn kan bá kú, irúfẹ́ orin tí àwọn ọ̀kọrin bá kọ lẹ́yìn ikú rẹ̀ àti bí irúfẹ́ orin bẹ́ẹ̀ ṣe jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà sí láàrin àwùjọ máa ń fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé akọni gbére ni ẹnìkan nígbà tí ó bá kú tán.

Ipa tí ẹ̀dá bá kó ní àárin àwùjọ kì í ṣe ohun tí ó máa ń lọ sí òkun ìgbàgbé. Bí àwọn èniyàn àwùjọ kò tilẹ̀ mú ìwé àti gègé láti kọ nípa ìtàn ẹnìkan sílẹ̀, ohun tí ó dájú ni pé wọ́n máa ń kọ ìwà àti ìṣe ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan sí inú ọpọlọ wọn. Wọ́n sì máa ń rán an ní àrántúnran fún gbogbo àwọn ìràn wọn tí ó bá ń wá sí ayé. Akọni ní àwùjọ Yorùbá ni

àwọn ẹ̀dá àwùjọ tí wọ́n kó ipa akínkanjú láàrin àwùjọ, tí wọ́n sì ní orúkọ rere nínú ìtàn. Àjùwọ̀n (2017) ṣe àlàyé pé ènìyàn lè jẹ́ akọni níbi ogun jíjà, ètò ìṣèlú, ìṣòwò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Èyí ni pé bí ènìyàn bá ja ogun tí ó ṣẹ́gun; akọni ni, bí ènìyàn bá ṣe ètò ìṣèlú ìlú ní àṣeyọrí; akọni ni, bí ènìyàn bá ṣòwò ní àrà ọ̀tọ̀, tí ó sì jèrè, tí ó sì dí olórúkọ ńlá; akọni ni, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀.

Ọ̀kan nínú àwọn ohun tí ó lè sọ ẹ̀dá àwùjọ kan di akọni ni ipa tí onítọ̀hun kó nínú ètò ìṣèlú àwùjọ bẹ́ẹ̀. Èyí kan ipò tí ó dì mú, bẹ́bẹ́ tí ó gbé ṣe, bí àṣìkò rẹ̀ ṣe rí àti àtunbọ̀tan onítọ̀hun lórí ipò náà. Bí àwọn nǹkan wọ̀nyí bá mú ìdẹ̀rùn, ìdẹ̀ra àti ìlọsíwájú bá àwọn ènìyàn àwùjọ ọ̀hún, wọn yóó rí ẹ̀dá tí o túkọ̀ ìṣèlú gẹ́gẹ́ bí akọni nítorí pé kì í ṣe ohun tí ó rọrùn ni láti túkọ̀ ìṣèlú àwùjọ. Ìdí tí àwọn akínkanjú òṣèlú fi jẹ́ akọni ni pé wàhálà tí ó rọ̀ mọ́ ètò ìṣèlú pọ̀ láti orí ipò dídù, bíbọ̀ sí orí ipò, ìforírán àti ìdàyàkọ gbogbo ìṣòro àwùjọ àti fífi iṣẹ́ rere lólẹ̀ fún ìtẹ̀síwájú àwùjọ. Ipò akọni tọ́ sì ẹni tí ó bá lè la gbogbo àwọn nǹkan wọ̀nyí já nínú ètò ìṣàkóso ìlú.

Lára ohun tí ó máa ń jẹ́ èrè̀njẹ fún jíjẹ́ akọni láàrin àwùjọ yálà nínú òṣèlú tàbí ní ọ̀nà mìíràn ni kí orúkọ wọn má parẹ́ nígbà tí wọ́n bá kúrò láyé. Èyí ni wọ́n máa ń rí bí nǹkan pàtàkì tí àwọn fi sílẹ̀ sáyé. Ọ̀pọ̀ àwọn adarí gidi nínú ètò ìṣèlú tilẹ̀ gbà pé fífi orúkọ rere sílẹ̀ yìí jẹ́ ogun ìní àwọn tí ọmọ le jẹ. èyí ni wọ́n fi máa ń sọ pé, ‘Ó fi orúkọ rere sílẹ̀ de ọmọ’. Èyí tí ó túmọ̀ sí pé bí onítọ̀hún kò bá tilẹ̀ sí láyé mọ, orúkọ rere tí ó fi sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí akọni yóó wà gbéré tàbí wà títí láéláé, àwọn ọmọ àti àrọ́mọdọ́mọ rẹ̀ yóó sì máa jèrè rẹ̀ títí ayé. Èyí sì ni ó fà á tí iṣẹ́ yìí fi tọ́ka sí irúfẹ́ àwọn akọni bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ bí akọni-gbére.

Fífi àròfọ̀ dárò òkú jẹ́ ohun tí ó gbilẹ̀ ní àwùjọ àwọn Yorùbá (Adeoye (1980), Àjùwọn (1981), Àmàó (1988), Ajíbáde (2010) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ipa tí lítírèṣọ̀ alohùn Yorùbá ń kó nínú sísọ àwọn ẹni tí ó bá jẹ́ akínkanjú láàrin àwùjọ di akọni-gbére kò kéré rárá. Ìdí ni pé, nípasẹ̀ lítíréṣọ̀ nípa fífi orúkọ wọn àti iṣẹ́ ribiribi tí wọ́n ṣe nígbà ayé wọn kọ orin, fífi orúkọ wọn àti ipa rere tí ìgbé ayé wọn mú bá àwùjọ wọn ké ewì tàbí fífi orúkọ wọn ṣe ìgbéjáde ìwé lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ máa ń sọ irúfẹ́ àwọn ẹni bẹ́ẹ̀ di ẹ̀dá mánigbàgbé. Ní àwùjọ Yorùbá, ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn ẹ̀yà lítíréṣọ̀ tí wọ́n máa n lò fún ìdárò òkú ni orin. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí orin jẹ́ máyàmí àwọn Yorùbá, gẹ́gẹ́ bí èrò Adémúyìwá (2017), Akínwùmí (2015, 2023), Ajíbádé (2007, 2020), Beier (1956), wọ́n fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé orin ṣe pàtàkì ní àwùjọ Yorùbá. Irúfẹ́ àwọn orin tí wọ́n bá sì lò láti dárò òkú ni orin ìdárò.

## Tíọ́rì Àmúlò - Tíọ́rì Ìmọ̀ Ìtàn (Historicism)

Tíọ́rì Ìmọ̀-Ìtàn (Historicism) ni tíọ́rì àmúlò fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ ìwádìí yìí. Tíọ́rì yìí jẹ́ tíọ́rì tí ó ń fúnka mọ̀ ìfìdí-òtítọ́-múlẹ̀ nípa ìtàn àwùjọ. Àwọn tí ó jẹ́ agbáterù tíọ́rì yìí fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-lítíréṣọ̀ ni Gallagher àti Greenblatt (2000), Levine (2022), Shittu àti Ayinla (2022), Zhuravleva (2022), Carte (2026). Tíọ́rì yìí ń wo ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàrin ìtàn gidi, àṣà àwùjọ àti lítíréṣọ̀. Tíọ́rì Ìmọ̀-Ìtàn rí lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bí ohun tí ó jẹ́ èsọ ìtàn àti àṣà àwùjọ, èyí tí kì í ṣe ohun tí ó dá dúró láàrin àwùjọ.

Ìdí pàtàkì tí ó jẹ́ kí a yan tíọ́rì yìí láàyò fún iṣẹ́ ìwádìí yìí ni pé tíọ́rì yìí wúlò fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́-lítíréṣọ̀ nípa ṣiṣọ ìṣẹ̀lẹ̀ inú lítíréṣọ̀ mọ́ ìtàn gidi tí ó ṣẹlẹ̀ láàrin àwùjọ. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí lọ́pọ̀ ìgbà, ìfìdímulẹ̀ ìtàn àwùjọ máa ń jẹ́ ìlépa lítíréṣọ̀. Tíọ́rì yìí yóó jẹ́ kí a lè tọpinpin ìtàn àwọn akọni-gbéré, kí a sì ṣe àmúlò ìtàn gidi nípa wọn láti fi ìdí ohun tí àwọn ọ̀kọrin sọ nípa wọn nínú orin wọn múlẹ̀. Èyí yóó sì jẹ́ ẹ̀rí máa jẹ́ mi nìṣó lórí àwọn àbùdá tí ó sọ àwọn àkàndá ènìyàn náà di akọni-gbére.

## Àfihàn Akọni nínú Orin Gbéré Yorùbá

Ní ilẹ̀ Yorùbá bí ẹni tí ó jẹ́ akọni ènìyàn bá kú, onírúurú àwọn ọ̀kọrin ní ó máa kọ orin nípa onítọ̀hún. Èyí sì máa ń ṣe àfihàn ẹni tí ó kú náà gẹ́gẹ́ bí akọni. Àwọn kókó-èrò tí ó máa ń jádé nínú àwọn orin tí wọ́n bá kọ fún ìdárò òkú máa ń jẹ́ àwọn kókó-èrò tí ó

máa ń ṣàlàyé nípa ẹni tí ó kú jẹ́, ipò rẹ̀ láàrin àwùjọ àti ìdí tí àwùjọ fi rí onítọ̀hun gẹ́gẹ́ bí akọni. Lára àwọn kókó-èrò bẹ́ẹ̀ tí iṣẹ́ yìí ṣe àfàyọ ni ìdárò ikú akọni, ìtọ́kasí irúfẹ́ ikú tí ó pa wọ́n, ìtọkásí ẹni tí ó kú gẹ́gẹ́ bí ènìyàn ńlá, ipò tí òkú dì mú nígbà tí ó wà láyé àti bẹbẹ tí ó gbé ṣe lórí ipò náà.

## Ìdárò Ikú Akọni

Bí ènìyàn bá kú láàrin àwùjọ, bí wọ́n bá ṣe dárò ikú ẹni náà sí máa ń ṣe àfihàn bí onítọ̀hún ṣe ṣe pàtàkì sí nígbà tí ó wà láyé. Ikú ẹni tí ó bá jẹ́ akọni máa ń mi ìlú tìtì, ó sì máa ń ká àwọn ènìyàn lára, ìmọ̀lára wọn sì máa ń fi han pé ẹ̀dùn ọkàn ni ikú ẹni bẹ́ẹ̀ mú bá wọn. Bí ó bá jẹ́ ènìyàn kan yẹpẹrẹ ni ó kú, yàtọ̀ sí pé ìmọ̀lára àwùjọ nípa ikú rẹ̀ kò ní rinlẹ̀ bíi ti ikú akọni, àwọn ọ̀kọrin gan-an kò ní ka kíkọ orin nípa ikú ẹni bẹ́ẹ̀ kún nǹkan tí ó ṣe bàbàrà. Àpẹẹrẹ ìdáro ikú akọni ni:

Ègbè: Lokacin da Múrítàlá ya mutu
Àjọkọ: Mutu mu da yaa sun yay kuka
Lokacin da Múrítàlá ya mutu
Lílé: Tọmọdé tàgbà ni wọ́n ń sunkún ojú
Ègbè: Lọ́jọ́ tí Múrítàlá jáde láyé
Lílé: Tọmọdé tàgbà ni wọ́n ń sunkún ojú
Ègbè: Lọ́jọ́ tí Múrítàlá jáde láyé
Lílé: Mùtú mútu kíkeya dèkí a láira
Ègbè: Ènìyàn pàtàkì lọ
Láílaha ílà lahù Múrítàlá Muhọ́mọdù a ò ri mọ́
Lílé: Ìba kó dì dán Kánò
Ègbè: Dúkà sírí ń kúká á á á
Lílé: Ìba ko di dan Kánò
Ègbè: Dúkà sírí ń kúká á á á
Lílé: Lọ́jọ́ tán ń gbé Múrí lọ síbojì
Ègbè: Tonílé tàlejò ní Kánò ń sọkún fu lórí ìtẹ́
Láílaha ílà lahù Múrítàlá Muhọ́mọdù a ò ri mọ́
(Hárúnà Ìṣọ̀lá - *Late Gen. Muritala Muhammed*)

Orin òkè yìí jẹ́ orin tí Hárúnà Ìṣọ̀lá kọ́ láti ṣe ìdáro Ọ̀gágun Múrítàlá Ramat Muhammed. Ọ̀gágun Múrítàlá jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọ̀gá ológun ti wọ́n yọ̀nda ẹ̀mí wọn fún ikú nítorí kí oríẹ̀-èdè yìí lè wà ní ìrẹ́pọ̀, ó jà fita-fita lójú ogun ní àṣìkò ogun abẹ́lé ti wáyé ní ilẹ̀ yìí. Ọ̀gágun Múrítàlá Ramat Muhammed ni olórí orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní àṣìkò ti wọ́n ṣe ikú pa á. Inú làásìgbò ìdìtẹ̀gbàjọba tí ó wáyé ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní ọjọ́ kẹtàlá, oṣù kejì, ọdún 1976 (13th Februrary, 1976) ni àwọn ọmọ ogun kan tí wọ́n gbìyànjú láti dìtẹ̀ gbà ìjọba orílẹ̀-èdè yìí pa Ọ̀gágun Múrítàlá Ramat Muhammed sí (Panter-Brick, 1978; Oyediran, 1979; Ali, 1982; Garba, 1982; Olajide, 2020; Siollun, 2009). Ìdìtẹ̀gbàjọba tí ó wáyé yìí forí sánpọ́n lẹ́yìn tí wọ́n ti pa Ọ̀gágun Muritala Ramat Muhammed tí ó jẹ́ olórí orílẹ̀-èdè tán, èyí ni ó sì jẹ́ kí Ọ̀gágun Olúṣẹ́gun Ọbásanjọ́ di olórí orílẹ̀-èdè ní ọdún 1976 lẹ́yìn ikú Ọ̀gágun Muritala Ramat Muhammed. Lára orin mìíràn tí ọ̀kọrin yìí tún fi dárò ikú akọni yìí ni:

Lílé: Ọkùnrin ọ̀gbágbárá wọnú ilẹ̀ o
Ègbè: Ọkùnrin gbọ̀rọ̀gọ̀dọ̀
Múrí dẹni à ń fẹkún gbè
Láílaha ílà lahù Múrítàlá Muhọ́mọdù a ò ri mọ́

Àwọn àyọlò orin Hárúnà Ìṣọ̀lá òkè yìí fi hàn pé gbogbo ará orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni ikú Ọgágun Múrítàlá Ramat Muhammed jẹ́ ẹ̀dùn ọkàn fún, gbogbo wọn ni wọ́n sì dárò nígbà tí wọ́n gbọ́ ikú rẹ̀.

Bákan náà, ni wọn fi orin ṣe ìdárò Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ ẹni tí ó tí ó jẹ́ Premier ìjọba Ìwọ-Oòrùn (Western Region) Nàìjíríà ijọ́hun ní ìgbà ayé rẹ̀. Orin náà lọ báyìí:

Lílé: Àjànàkú sùn bí òkè
Erin ṣubú kò mà lè dìde
Ègbè: Áàwolọ́wọ̀, ó di gbéré...
Lílé: Ẹni bá magbe
Ègbè: Kó ṣèdárò aró
Lílé: Ẹni bá màlùkò
Ègbè: Kó ṣèdárò osùn
Lílé: Ẹnikẹ́ni tó bá mọ lèkélèké
Ègbè: Kó ṣèdárò ẹfun báláú
(Sunny Ade - 'Late Papa Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ S.A.N.' nínú *Jealosy*)

Orin òkè yìí jẹ́ orin tí King Sunny Adé kọ́ láti ṣe ìdáro Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀, ẹni tí ó kú ní ọdún 1987. Koko-èrò ohun tí ọ̀kọrin sọ nínú orin náà ni pé ẹni tí ó bá mọ Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ kí ó dárò ikú rẹ̀. Àpẹẹrẹ mìíràn tún ni orin ìsàlẹ̀ yìí tí ọ̀kọrin fi ki *Olóògbé Ọba Joel Adébóyè* tí ó jẹ́ ọba Orímọlúsì Ìjẹ̀bú-Igbó nígbà kan:

Lílé: Ìjẹ̀bú-Ugbó!
Ọ̀rọ̀ yìí kàyífì ni o, Sáátì!
Baba Démọ́lá ṣe bẹ́ẹ̀ ó wàjà
Igbó máràárún tÓlúmosì ni
Lílé: Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀
Ijọ́ yó gbọ́
Ó fọwọ́ gbárí pẹ́ pẹ́
Ó lỌba Adébóyè ló jáde láyé
Baba Morádéhún
Àfi tọ́n bá gbé e bọ̀
(Hárúnà Ìṣọ̀lá - *Late Ọba Joel Adébóyè*)

Hárúnà Ìṣọ̀lá ni ó kọ orin òkè yìí láti dárò ikú Olóògbé Ọba Joel Adébóyè. Olóògbé Ọba Joel Adébóyè jẹ ọba Orímọlúsì Ìjẹ̀bú-Igbó ní ọdún 1947, ó sì kú ní ọdún 1955. Hárúnà Ìṣọ̀lá fi orin òkè yìí dárò ikú Ọba yìí nípa títọ́kasí bí ó ti jẹ́ pé gbogbo ayé ni ó dárò rẹ̀. Láti fi hàn pé ìdárò ikú ọba yìí rinlẹ̀ ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, Hárúnà Ìṣọ̀lá tọ́ka sí àwọn bí Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀, tí wọ́n jẹ́ ènìyàn pàtàkì àti akíkanjú láàrin ìlú ni àṣìkò ti ọba yìí kú, gẹ́gẹ́ ọ̀kan lára àwọn ti wọ́n ṣe ìdárò ikú Ọba yìí.

**Ìtọ́kasí Irú Ikú tí ó pa wọ́n**

Ọ̀kan nínú àwọn ohun tí ó máa ń jẹ́ àbùdá àwọn akọni ni pé ikú wọn kì í ṣáábà jẹ́ ikú jẹ́ẹ́jẹ́ tàbí ikú bòńkẹ́lẹ́ tí ẹnìkan lè dọwọ́ bò pé kí arayé má mọ irú ikú tí ó pa wọ́n. Ìtọ́kasí irú ikú tí ó pa wọ́n yìí máa ń jẹ yọ nínú orin tí àwọn ọ̀kọrin bá kọ láti ṣe ìdárò ikú àwọn akọni gbére. Àpẹẹrẹ nìyí nínú orin ìsàlẹ̀ yìí:

Lílé: Ìlú Òyìnbó ná lọ
Wọ́n lọ̀pàdé ọ̀rọ̀ kòkó ni
Àjọkọ: Wọ́n ń bọ̀, kíṣẹ́ tó ṣe

Wọ́n ti dé Jàmíkà kọ́lọ́jọ tó dé
Adébóyè ọmọ Àdòrò-òkè, bọ́rọ́kọ́tọ́ bí ọká
Àkòtakìjí Erin-ńlá tí ń migbó
Ó lọ
Atẹ́gùn ló fa sábàbí ọkọ̀
Fọ́mọ Olú fọwọ́ è ṣé bèyẹn
Tíripolì ni wọ́n dé?
Àjọkọ: Ọkọ̀ yìí fẹ́ bà sílẹ̀ lafẹ́fẹ́ ńlá dé
Ọkọ̀ yìí forí sọgi
Nígbà tó já lojúù sánmọ̀
Kó tóó délẹ̀
Ó gbaná ẹ̀mí rọ̀run
Lílé: Bọ́jọ́ bá ti pé
Àjọkọ: Oníṣègùn tó lè yẹ̀ ẹ́ ò sí o
Kádàrá!
Ọkọ̀ ojú sánmọ̀ lókè
Ló wa Adébóyè sájùlé ọ̀run
(Hárúnà Ìṣọ̀lá - *Late Ọba Joel Adébóyè*)

Ó hàn nínú orin òkè yìí pé nípasẹ̀ ọkọ̀ òfurufú bàálù tí ó jábọ́ ni Ọba Joel Adébóyè ni ọba yìí ṣe kú ní ọdún 1955. Ìlú Òyìnbó ni ọba yìí àti àwọn ènìyàn pàtàkì mìíràn lọ láti lọ ṣe ìpàdé nípa ọ̀rọ̀ òwò kòkó èyí ti ọrọ̀-ajé ìjọba ìwọ̀-oòrùn orílẹ̀-èdè yìí rọ̀gbọ̀kú lé ní ìgbà náà. Nígbà tí wọ́n dé Tíripolì ní afẹ́fẹ́ ṣe ọwọ́ òdì sí bálùú wọn, tí ó sì jábọ̀. Ọkọrin tẹ̀ṣíwájú láti tọ́ka sí àwọn tí wọ́n jọ kọ́wọ̀ọ́ wọ bàlúù náà, tí ìṣẹ̀lẹ̀ sì jọ mú ẹ̀mí wọn lọ. Èyí hàn nínú orin ìsàlẹ̀ yìí:

Ègbè: Àlí Àtàndá lọ ní Kánò
Asán nilé ayé
Ikú tó ń pa tálákà ló ń polówó
Tọ́n bá ń rira ní Kìyómọ̀
Àlí bá wa kí Màkọ́lì
Adébóyè bá wa kí Bọ̀dé lọ́run
(Hárúnà Ìṣọ̀lá - *Late Ọba Joel Adébóyè*)

Ó hàn nínú àyọlò òkè yìí pé Àlí Àtàndá láti ìlú Kánò jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn tí ẹ̀mí wọn bọ́ nínú ìjàmbá bàlúù náà. Àpẹẹrẹ mìíràn tún nìyí nínú àyọlò ìsàlẹ̀ yìí:

Adélabú, ó lóun ọ́ rọ̀nà Èkó,
Asàráìlù ló lọ̀ọ́ dènà fún un,
O kù dẹ̀dẹ̀ kó wolúyọ̀lé lọ́lọ́jọ́ dé o!
Ǹ jẹ́ ọ́ yẹ ká dẹ tàkúté de ra a wa?
(Odòlayé Arẹ̀mú - *Ikú Akíntọ́lá*)

Orin òkè yìí tọ́ka sí irú ikú tí ó pa Adégòkè Adélábú àgbà olóṣèlú ilẹ̀ Ìbàdàn tí gbogbo ènìyàn mọ̀ sí Adélábú Pẹnkẹlẹmẹ́ẹ̀sì tí ó kú ní ọdún 1978 nípasẹ̀ ìjànbá ọkọ̀. Adégòkè Adélábú jẹ́ ọ̀kan lára àwọn akíkanjú ti wọ́n ja ìjà òmìnira orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Ìlú Èkó ni Adégòkè Adélábú Pẹnkẹlẹmẹ́ẹ̀sì lọ, nígbà tí ó ń bọ̀ wálé, bí ó ṣe fẹ́ wọ ìlú Ìbàdàn ni ọkọ̀ àjàgbé kọ lù ú, tí ó sì pa á. Nínú èrò Odòlayé Arẹ̀mú tí ó kọ orin òkè yìí, ó gbà pé wọ́n mọ̀-ọ́n-mọ̀ dẹ ọkọ̀ àjàgbé náà láti ṣọ̀nà de Adégòkè Adélábú Pẹnkẹlẹmẹ́ẹ̀sì ni. Ìdí nìyí tí ó fi sọ pé "Ǹ jẹ́ ọ́ yẹ ká dẹ tàkúté de ra a wa?".

Bákan náà, Odòlayé Arẹ̀mú tọ́ka sí irúfẹ́ ikú tí ó pa Àarẹ Samuel Ládòkè Akíntọ́lá nínú àyọlò orin ìsàlẹ̀ yìí:

À ń pé kí an mọ́ pà á, wọ́n pa á dandan dan!
Wọ́n pagbe tán, ayé ò ráró dá mọ́ oo!
Wọ́n sì pa Àlùkò tán ayé ò kosùn!
Wọ́n wá pa lèkélèké ayé ò gbádùn ẹfun!
À ń pé kí an mọ́ pà á, wọ́n pa á dandan dan!
Wọ́n wá á pa gúnnugún ayé ò gún mọ́ o!
Wọ́n sì pa Àkàlàmọ̀gbò tán ayé ò kalẹ̀!
Bí àtàtà èèyàn bá kú, ó yẹ kó dàámú ìlú o!
Ẹ wo ikú ọlọ́lá bí ti ń lé gbogbo ọmọ ará-ayé kiri!
(Odòlayé Arẹ̀mú - *Ikú Akíntọ́lá*)

Àarẹ Samuel Ládòkè Akíntọ́lá tí ọ̀kọrin tọ́ka sí nínú orin òkè yìí jẹ́ olórí ìjọba Ìwọ̀-Oòrùn Nàìjíríà (Premier Western Region), òun sì tún ni Àarẹ-ọnà-Kakaǹfò kẹ́tàlá nígbà ayé rẹ̀. Àarẹ-ọnà-Kakaǹfò yìí ni olórí ọmọ-ogun ilẹ̀ Yorùbá. Ó hàn nínú àyọlò orin òkè yìí pé pípa ni wọ́n pa Àarẹ Samuel Ládòkè Akíntọ́lá. Àarẹ Samuel Ládòkè Akíntọ́lá kú ní ọjọ́ kẹ̀ẹ̀ẹ́dógún, oṣù kín-ín-ní, ọdún 1966 (15th January, 1966) nípasẹ̀ ìdìtẹ̀ gbàjọba tí ó wáyé ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní ọdún 1966.

**Ìtọ́kasí Òkú gẹ́gẹ́ bí Ẹni-Ńlá**

Láti fi hàn pé akọni gbére ni ẹnìkan, ó gbọdọ̀ jẹ́ ènìyàn pàtàkì tí a lè pè ní akọni láàrin ìlú nígbà tí ó wà láyé, nígbà tí ó bá sì kú tí orúkọ rẹ̀ kò bá parẹ́ ni ó tó di akọni gbére. Àwọn ọ̀kọ̀rin tí wọ́n ń kọrin láti dárò àwọn akọni gbére máa ń tọ́ka sí ipò tí irúfẹ̀ àwọn akọni bẹ́ẹ̀ dì mú nígbà tí wọ́n wà láyé. Àpẹẹrẹ hàn nínú àyọlò ìsàlẹ̀ yìí:

Lílé: Mo dénú igbó o
Igbó pa lọ́lọ́
Ègbè: Mo béèrè kí ló ṣegbó o
Kó tó pa lọ́lọ́?
Lílé: Wọ́n lólórí igbó o ló fayé sílẹ̀
Ègbè: Láílaha ílà lahù Múrítàlá Muhọ́mọdù a ò ri mọ́
Lílé: Mo dénú ọdàn-àn
Ọdàn ń mì tìtì
Ègbè: Mo ní kí ló ṣọdàn
Tọ́dàn ń mì tìtì?
Lílé: Wọ́n lólú ọdàn ló fayé sílẹ̀
Ègbè: Láílaha ílà lahù Múrítàlá Muhọ́mọdù a ò ri mọ́
Lílé: Mo débi omi
Ibú ṣomi kánrin kése e
Ègbè: Mo ní kí ló ṣebú
Tó ṣomi kánrin kése?
Lílé: Wọ́n lárògìdìgbà ló fayé sílẹ̀
Ègbè: Láílaha ílà lahù Múrítàlá Muhọ́mọdù a ò ri mọ́
Lílé: Èkò di bó ò lọ yàgò lọ́nà kí n lọ
Ègbè: Lọ́jọ́ Jímọ̀ tí Múrí jáde láyé é
Lílé: Èkò di bó ò lọ yàgò lọ́nà kí n lọ

Ègbè: Lọ́jọ́ Jímọ̀ tí Múrí jáde láyé é
Lílé: Fẹ̀búárì 13, 1976
Ègbè: Láílaha ílà lahù Múrítàlá Muhọ́mọdù a ò ri mọ́
(Hárúnà Ìṣọ̀lá - *Late Gen. Muritala Muhammed*)

Orin òkè yìí júwe irúfẹ́ ènìyàn tí Ọ̀gágun Múrítàlá Muhammed jẹ́ nígbà tí ó wà láyé. Fífi Ọ̀gágun Múrítàlá Muhammed wé olórí igbó, olórí ọ̀dàn àti àrọ̀gìdìgbà fi hàn pé akíkanjú àti ènìyàn ńlá ni. Èyí ni pé bí olórí igbó ṣe jẹ́ akọni nínú igbó, tí olórí ọ̀dàn jẹ́ akọni nínú ọ̀dàn, tí àrọ̀gìdìgbà jẹ́ akọni nínú omi, bẹ́ẹ̀ náà ni Ọ̀gágun Múrítàlá Muhammed ṣe jẹ́ akọni pàtàkì ní àwùjọ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Èyí ni ó fà á tí ó fi jẹ́ pé nígbà tí wọ́n pa Ọ̀gágun Múrítàlá Muhammed tan ní ọjọ́ kẹtàlá, oṣù kejì, ọdún 1976 (13th Februrary, 1976), gbogbo ìlú Èkó, èyí tí ó jẹ́ olú-ìlú orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní ìgbà náà kò fara rọ.

Èèkàn kàn-kàn-ràn ni Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ nínú ìṣèlú àti gbígba ilẹ̀ Nàìjíríà kúrò lọ́wọ́ ìṣèjọba àwọn òyìnbó amúnisìn. Ètò ìṣèjọba rẹ̀ mọ́yánlórí, ó sì mú ìlọsíwájú bá ilẹ̀ Yorùbá àti orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní àpọpọ̀. Àwọn nǹkan wọ̀nyí jẹ́ kí àwùjọ Yorùbá rí i bí olùgbàlà, nítorí ó ṣe ohun ti ẹnìkan kò ṣe rí nínú ètò ìṣèjọba ni àwùjọ ilẹ̀ yìí. Èyí ni wọ́n fi ṣe àfihàn Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ gẹ́gẹ́ bí ènìyàn ńlá ní àwùjọ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà nínú orin tí wọ́n fi ṣe ìdárò wọn ní ìsàlẹ̀ yìí:

Lílé: Gbogbo ọmọ Afíríkà o
Ègbè: Háà! Àràbà ńlá ya níjù
Ó ṣe e!
Lílé: Gbogbo ọmọ Nàìjíríà
Ègbè: Árábà ńlá ya níjù
Ó ṣe e!
Lílé: Gbogbo ọmọ Odùduwà pátá
Ègbè: Háà! Àràbà ńlá ya níjù
Ó ṣe e!
(Sunny Ade - 'Late Papa Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ S.A.N.' nínú *Jealosy*)

Fífi Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ wé àràbà nínú orin òkè yìí fi hàn pé ọ̀kan nínú àwọn òpó ìṣèlú ilẹ̀ Yorùbá, orílẹ̀-èdè Nàìjíríà àti ní gbogbo ilẹ̀ Áfíríkà lápapọ̀ ni. Èyí ni pé bí àràbà ṣe jẹ akọni igi nínú igbó náà ní Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ jẹ́ akọni ní àwùjọ ènìyàn. Èyí ni ó sì fà á tí ọ̀kọrin fi fi ikú Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ ní ilẹ̀ Áfíríkà wé yíya igi àràbà nínú igbó. Orin náà tún tẹ̀ṣíwájú báyìí pé:

Lílé: Jíjí tí mo jí nílùú Òyìnbó
Ègbè: Mo gbọ́ kowéè kan tó ń ké
Lílé: Jíjí tí mo jí nílùú Òyìnbó
Ègbè: Mo gbọ́ kowéè kan tó ké
Lílé: Jíjí tí mo jí nílùú Òyìnbó
Ègbè: Mo gbọ́ kowéè kan tó ké
Lílé: Mo ní kí ló dé tó ń ké láìha?
Ègbè: Ẹyẹ abàmì tó ń ké é
Lílé: Ó ké lẹ́ẹ̀kejì

Ègbè: Láìha láìha
Ẹyẹ abàmì tó ń ké
Lílé: Ó ké lẹ́ẹ̀kẹta
Ègbè: Láìha láìha
Ó ń kéké ìyanu
Ó ń ṣèṣe ìyanu
Ẹyẹ abàmì ló ń ké é
Lílé: Àmì ara sọ mí
Mo ránṣẹ́ sílé
Mo ní kí ló ṣẹlẹ̀?
Ègbè: Wọ́n ní erin ti wó
Ó wó, ó wó, ó wó ó
Lílé: Àjànàkú sùn bí òkè
Erin ti wó kò lè dìde
Ègbè: Ááwolọ́wọ̀, ó di gbéré
Lílé: Àjànàkú sùn bí òkè
Erin ṣubú kò mà lè dìde
(Sunny Ade - 'Late Papa Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ S.A.N.' nínú *Jealosy*)

Ní ilẹ̀ Yorùbá, ohun àmì ni ó jẹ́ nígbà tí ẹyẹ kowéè bá ké ṣùgbọ́n tí kó hà. Bí irú èyí bá wáyé, ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé ìṣẹ̀lẹ̀ ńlá kan ti ṣẹlẹ̀, ẹni ńlá kan ti kú. Irúfẹ́ èrò yìí ni King Sunny Ade gbé kalẹ̀ nínú orin òkè yìí láti ṣe àfihàn pé ènìyàn ńlá ni Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ tí ó jáde láyé. Bákan náà ni ọ̀kọrin tún fi kíkú Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ wé wíwo erin nínú igbó. Èyí túmọ̀ sí pé bí erin ṣe jẹ ọba ẹranko ni Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ jẹ́ akọni ènìyàn.

Yàtọ̀ sí èyí, ìfihàn pé ènìyàn pàtàkì ni Olóògbé Ọba Síkírù Káyọ̀dé Adétọ̀nà Awùjalẹ̀ ti Ìjẹ̀bú-Òde tí ó kú ní ọdún 2025 ní àwùjọ ilẹ̀ Yorùbá àti orílẹ̀-èdè Nàìjíría lápapọ̀ hàn nínú orin tí Ebenezer Obey fi ṣe ìdárò rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú orin ìsàlẹ̀ yìí:

Àjọkọ: Kò sẹ́ni tí ó ní san
Kò sẹ́ni tí ó ní san
Igbèsè nikú, Baba Morádéhún
Kò sẹ́ni tí ó ní san
Lílé: Erin ńlá wó ó
Àjànàkú lọ lọ́dàn ó ṣe
Àjọkọ: Káàsà! Ìjẹ̀bú-Ugbó
Ẹ mà kú etíìgbọ́
Ẹ kú ilédè ọkọ Modúpẹ́ Orímolúsì
Kábíèsí tó lọ sájùlé ọ̀run

Lílé: Ẹni ò lè ṣe bí aláarùn lóyìngbò
Àjọkọ: Íyẹ́n ò lè ṣe bí Adégbọrọ̀ lọ́jà ọba ò
Àjọkọ: Àdá tó mú sánsán kò le sánko fún ra rẹ̀
Ènìyàn lo le sánko fún un
Ewé ńlá-ńlá o
Ewé ńlá-ńlá o

kò ní padà, kó rú wẹ́wẹ́
Èèwọ̀ òrìṣà!
(Ebenezer Obey – Orin tí wọ́n kọ níbi àdúrà ọjọ́ kẹjọ́ Ọba Síkírù Káyọ̀dé Adétọ̀nà)

Orin òkè yìí ni Ebenezer Obey kọ léyìn ikú Olóògbé Ọba Síkírù Káyọ̀dé Adétọ̀nà Awùjalẹ̀ ti Ìjẹ̀bú-Òde. Ọba Káyọ̀dé Adétọ̀nà jẹ́ ọ̀kan lára àwọn awùjalẹ̀ Ìjẹ̀bú-Òde ti wọ́n fi kún òkìkí àti ìdàgbàsókè Ìjẹ̀bú-Òde àti ilẹ̀ Ìjẹ̀bú ní àpapọ̀. Gẹ́gẹ́ bí ìwé ìròyìn *The Punch* (July 13, 2025) àti *The Guardian* (July 25, 2025) ṣé ṣàlàyé, Ọba Síkírù Káyọ̀dé Adétọ̀nà jẹ ọba Awùjalẹ̀ ti ìlú Ìjẹ̀bú-Òde ní ọjọ́ kejì, oṣù kẹrin ọdún 1960 (2nd April, 1960) nígbà tí ó wà ní ọmọ ọdún mẹ́rìndínlọ́gbọ̀n (26), ó sì kú ní ọjọ́ kẹtàlá, oṣù keje ọdún 2025 (13th July, 2025) ní ẹni ọdún mọ́kànléláàádọ́rùn-ún (91years) (The Guardian, July 13, 2025). Èyí fi hàn pé Ọba Síkírù Káyọ̀dé Adétọ̀nà ló ọdún márùndínláàádọ́rin (65years) ní orí àpèrè ọba Awùjalẹ̀ ti ìlú Ìjẹ̀bú-Òde. Ebenezer Obey fi Olóyè Ọba Síkírù Káyọ̀dé Adétọ̀nà wé erin ńlá tí ó tún dà pè ní àjànàkú. Èyí túmọ̀ sí pé bí erin ṣe jẹ ọba ẹranko ni Ọba Síkírù Káyọ̀dé Adétọ̀nà jẹ́ ọba ní àwùjọ ènìyàn. Ọ̀kọrin tún pé Ọba Síkírù Káyọ̀dé Adétọ̀nà ní ewé ńlá nínú orin náà, èyí tí ó sọ pé " Ewé ńlá-ńlá kò ní padà, kó rú wẹ́wẹ́". Eyí túmọ̀ sí pé bí Ọba Síkírù Káyọ̀dé Adétọ̀nà ṣe tobí tó, kò lè padà di ẹni yẹpẹrẹ kódà lẹ́yìn ìgbà tí ó kú tán. Èyí sì fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé akọni-gbére ni Ọba Síkírù Káyọ̀dé Adétọ̀nà.

Àpẹẹrẹ mìíràn tú ni orin tí wọ́n fi ki Olóyè Símbìàtù Abíọ́lá nínú àyọlò ìsàlẹ̀ yìí:

Lílé: Lọ́jọ́ tán gbé Símbìàtù dé
Tí wọ́n gbé e dé látìlú Ọba
Kódà bó jólórí-ìlú ni
Kò lè yẹ é ju Símbìàtù lọ
Ayé yẹ́ é, aya Ọláwálé
Kọ̀run dáa fún ẹ jù bẹ́ẹ̀ lọ
Olórí-ìlú, gbogbo wọ́n ná wá
Látorí olórí-ìlú orílẹ̀-èdè wa
Bùráímọ̀ ọmọ Bàbáńgídá
Àwọn gọ́fánọ̀ pọ̀ lọ jàra
Àwọn mínísítà wọn pọ̀ lọ bìbà o
Àǹbásádọ̀, wọ́n pọ̀ lọ bí i rẹ́rẹ
Àwọn Mùsùlùmí lọ bí ọlá Ọlọ́hun
Àwọn Onígbàgbọ́ ò lóǹkà o
Mẹ̀kúnnù wọ́n pọ̀ lọ jàra
Ọmọ ilékéú ò lónkà o
Àlìhúlàmọ́hù, wọ́n lọ bíi rẹ́rẹ́
Àyìndé Adé lójú mi ló ṣé
Ẹ wobi kéú gbé ń kù bí òjò o
(Síkírù Àyìndé Barrister - ‘Late Ayinba Simbiat Abíọ́lá’ nínú *Fuji Dimension*)

Orin òkè yìí ni Síkírù Àyìndé Barrister fún ìdárò ikú lẹ́yìn ikú Olóògbé Alhaja Simbiat Abíọ́lá ẹni tí ó jẹ́ ìyáwò Olóògbé Ààrẹ Moshood Kásìmáawòò Abíọ́lá tí ó wọlé ìbò Ààrẹ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní ọdún 1993, ṣùgbọ́n tí wọn kò gbé ìjọba fún un. Alhaja Simbiat Abíọ́lá kú ní ọjọ́ kẹwàá, oṣù kọkànlá, ọdún 1992 (10th November, 1992) ní àṣìkò tí ọkọ rẹ̀ ń du ipò Ààrẹ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Ènìyàn ńlá ni Alhaja Simbiat Abíọ́lá,

akọnibìnrin sì ni pẹlú. Ohun tí ó fún ní orúkọ gan-an ni gbajúmọ̀ ènìyàn tí ọkọ rẹ̀ jẹ́. Yàtọ̀ sí èyí, Alhaja Simbiat Abíọ́lá tún jẹ́ oníṣòwò àtí onílé-iṣẹ́. Irúfẹ́ àwọn ọ̀wọ́ ènìyàn tí ọ̀kọrin mẹ́nu bà nínú orin òkè yìí pé wọ́n wá sí ibi ìsìnkú Alhaja Simbiat Abíọ́lá fi hàn pé Alhaja Simbiat Abíọ́lá kì í ṣe ènìyàn lásán láàrin àwùjọ.

**Ìpò Òkú kí ó tó kù**

Bí ènìyàn bá ènìyàn bá jẹ́ ẹni ńlá tàbí akọni pàtàkì láàrin ìlú, ó máa ní irúfẹ́ ipò tí onítọ̀hún dì mú nínú àwùjọ kí àwọn ènìyàn àwùjọ tó rí i gẹ́gẹ́ bí akọni. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn akọni inú ètò ìṣèlú ni a ṣàyàn nínú iṣẹ́ yìí, síbẹ̀ oní inú irúfẹ́ ètò ìṣèlú tí ẹnìkọ̀ọ̀kan wọn ti kópa, ó sì ní irúfẹ́ ipò tí wọ́n dì mú nínú ìlànà iṣẹ̀lú tí wọ́n ti kópa. Ìtọ́kasí ipò tí àwọn akọni gbére yìí dì mú láyé máa ń jẹ yọ nínú orin tí àwọn ọ̀kọrin bá kọ láti dárò wọn lẹ́yìn ikú wọn. Àpẹẹrẹ irúfẹ́ kókó-èrò bẹ́ẹ̀ ni:

Mo rántí olólùfẹ́ mi o,
Akíntọ́lá,
Premier Western Region
Bótò: Bàbá o!
Ikú oo, tí èé jẹ́ á dágbére fẹ́nìkejì ẹni
Kò tóó mọ́ ọn múni lọ
(Odòlayé Arẹ̀mú – *Ikú Akíntọ́lá*)

Nínú orin òkè yìí, Odòlayé Arẹ̀mú tọ́ka sí ipò tí Ààrẹ Samuel Ládòkè Akíntọ́lá dì mú nígbà tí ó wà láyé. Ipò yìí ni ipò olórí ìjọba Ìwọ̀-Oòrùn Nàìjíríà (Premier Western Region). Ipò yìí náà ni ipò tí Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ dì mú ṣáájú, kí ó tó di pé Ààrẹ Samuel Ládòkè Akíntọ́lá dé ibẹ̀. Èyí fi hàn pé nínú ètò ìṣèlú ìjọba àwaarawa (democracy) ni Ààrẹ Samuel Ládòkè Akíntọ́látí di ipò mú nígbà tí ó wà láyé.

Apẹẹrẹ mìíràn tún ni orin ìsàlẹ̀ yìí nípa ìtọ́kasí ipò ti Ọba Síkírù Káyọ̀dé Adétọ̀nà Awùjalẹ̀ ti Ìjẹ̀bú-Òde dì mú nígbà tí ó wà láyé:

Lílé: Síkirù Àyànfẹ́, Àwùjalẹ̀ ọ̀ba tótó
Ègbè: Síkirù Àyànfẹ́, Àwùjalẹ̀ ọ̀ba tótó
Lílé: Kábíyèsí ti wàjà, ó ti wàjà o!
Ègbè: Síkirù Àyànfẹ́, Àwùjalẹ̀ ọ̀ba tótó
Àjọkọ: Awùjalẹ̀ ọba tótó
Ègbè: Síkirù Àyànfẹ́, Àwùjalẹ̀ ọ̀ba tótó
Lílé: Kábíyèsí ti wàjà, ó ti wàjà o!
Ègbè: Síkirù Àyànfẹ́, Àwùjalẹ̀ ọ̀ba tótó
Lílé: Èdùmàrè kó dẹlẹ̀
kó dẹlẹ̀ fún bàbá tó relé
Ègbè: Síkirù Àyànfẹ́, Àwùjalẹ̀ ọ̀ba tótó
Lílé: Ọ̀gbágbá, a gbọ́tẹ̀ mọ́lẹ̀
Ègbè: Síkirù Àyànfẹ́, Àwùjalẹ̀ ọ̀ba tótó
(Ebenezer Obey – Orin tí wọ́n kọ níbi àdúrà ọjọ́ kẹjọ́ Ọba Síkírù Káyọ̀dé Adétọ̀nà)

Nínú orin òkè yìí, Ebenezer Obey tọ́ka sí ipò Ọba Síkírù Káyọ̀dé Adétọ̀nà gẹ́gẹ́ bí Awùjalẹ̀ ti Ìjẹ̀bú-Òde nígbà tí ó wà láyé. Èyí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé nínú ètò ìṣèlú ìbílẹ̀ (traditional politics/monachical system) ni Ọba Síkírù Káyọ̀dé Adétọ̀nà ti di ipò òṣèlú mú láàrin ọdún 1960 sí ọdún 2025, àgbà ọba sì ní ní gbogbo ilẹ̀ Ìjẹ̀bú (paramount king of Ìjẹ̀bú land). Nínú ètò ìṣèlú ìbílẹ̀ náà ni Oba Joel Adébóyè Orímọlúsì Ìjẹ̀bú-Igbó ọdún 1947 sí ọdún 1955, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú orin ìsàlẹ̀ yìí:

Baba Morádéhún
Àfi tọ́n bá gbé e bọ̀
Ègbè: Wọ́n ti lórí Adé ò ní sùnta
Lílé: Owó ńlá lọ
(Hárúnà Ìṣọ̀lá - *Late Ọba Joel Adébóyè*)

Ìpèdè pé 'Wọ́n ti lórí Adé ò ní sùnta' tí ó nínú orin òkè yìí fi hàn pé ọba ni Oba Joel Adébóyè Orímọlúsì Ìjẹ̀bú-Igbó, wọn kò sì gbọdọ̀ sin òkú rẹ̀ sí ẹ̀yìn odi. Èyí wà ní ìbámu pẹ̀lú àṣà àwùjọ Yorùbá àti ìgbàgbọ́ wọn nípa pé wọn gbọdọ̀ sin ọba kan sí ìlú tí ó ti jẹ ọba lẹ́yìn tí ó bá kú tan, wọ́n kò gbọdọ̀ sin ín sí ibòmíràn nítorí pé ọba gbọdọ̀ ní ojú-oórì ní ìlú rẹ̀.

Bí ó ti jẹ́ pé kì í ṣe ọkùnrin nìkan ní ó ń kópa nínú ètò ìṣèlú ìbílẹ̀ Yorùbá, tí ó jẹ́ pé àwọn obìnrin náà ní ipò tí wọ́n dì mú nínú ètò ìṣèlú ìbílẹ̀ Yorùbá, àwọn ọ̀kọrin náà tọ́ka sí ipò àwọn obìnrin tí ó ti kú náà nínú ètò ìṣèlú ìbílẹ̀ Yorùbá. Èyí hàn nínú orin Síkírù Àyìndé Barrister tí ó ti tọ́ka sí ipò Alhaja Simbiat Abíọ́lá báyìí:

Lílé: Símbìátù aya Abíọ́lá
Ìyálóde Kẹ́m̀ta kú o
Ègbè: Símbìátù aya Abíọ́lá
Tinúkẹ́ fayé sílẹ̀
Ọ̀tún Ìyálóde Líṣàbí
Àrìnnàkò ó dojú àlá á

Lílé: Lójú mi ló ṣe nílé Abíọ́lá
Ilé owó, ilé ọlá
Ilé ọgbọ́n, ilé òye
Nínú ọlá ńlá Símbìà
TAtinúkẹ́ ti ń pàṣẹ
Kó tó jáde rèlú ọba
(Síkírù Àyìndé Barrister - 'Late Ayinba Simbiat Abíọ́lá' nínú *Fuji Dimension*)

Ó hàn nínú orin òkè yìí pé Ìyálóde Kẹ́m̀ta Ẹ̀gbá ni Alhaja Simbiat Abíọ́lá. Bákan náà ni ó sì tún jẹ́ Ọ̀tún Ìyálóde Líṣàbí ní Ẹ̀gbá. Èyí fi hàn pé Alhaja Simbiat Abíọ́lá jẹ́ akínkanjú obìnrin tí ó ní ipa nínú ètò ìṣèlú ìbílẹ̀ ní àwùjọ Yorùbá. Yàtọ̀ sí èyí, ó tún hàn nínú orin náà pé apaṣẹ̀ ni Alhaja Simbiat Abíọ́lá nínú ẹbí. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nító rí pé òun ni ìyàlé àgbà ní ọ̀dẹ̀dẹ̀ ọkọ wọn.

**Bẹbẹ tí Òkú gbé ṣe**

Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé kí ènìyàn di ipò kan mú kò tó pọ́n, bí ohun tí ènìyàn gbé ipò náà ṣe. Wọ́n gbàgbọ́ pé tí ènìyàn bá lo ipò, tí ó fí orúkọ rere sílẹ̀ níbẹ̀ ni orúkọ ènìyàn kò fi ní parẹ́, tí ènìyàn yóò sì fi di akọni gbére lẹ́yìn tí ó bá kú tán. Nínú àwọn kókó-èrò nípa akọni gbére tí àwọn ọ̀kọrin máa ń fi hàn ni bẹbẹ tí ẹni náà gbé ṣe lórí ipò tí ó wà kí ó tó di pé ó kú. Àpẹẹrẹ ni orin ìsàlẹ̀ yìí:

Lílé: Nípa iṣẹ́ rere tí Múrítàlá ṣe sáyé
Ègbè: Ọmọ Nàìjíríà a ò ní gbàgbé rárá
Lílé: Nípa iṣẹ́ rere tí Múrítàlá ṣe sáyé
Ègbè: Ọmọ Nàìjíríà a ò ní gbàgbé rárá

Ègbè: Dárí ji Múrí tó dolóògbé o
Lílé: Olúwa Ọba
Ègbè: Dárí ji Múrí tó dolóògbé o
Lílé: Olótùú Ìjọba Àpapọ̀
Ègbè: Iṣẹ́ rere tó ṣe sáyé
Lílé: Ẹ tẹ́tí
Ègbè: Kí ẹ mí a gbọ́
Lílé: Ẹ tẹ́tí
Ègbè: Kí ẹ mí a gbọ́
Lílé: Gbogbo ohun tó le bí irin
Ègbè: Ó múyẹn dẹ̀ bí ẹ̀kọ
Lílé: Gbogbo ohun tó le bí irin
Ègbè: Ó múyẹn dẹ̀ bí ẹ̀kọ
Lílé: Ó ní gbogbo mẹ̀kúnnù
Ègbè: Nǹkankan ò gbọdọ̀ ni wọ́n lára
Lílé: Ó ní gbogbo mẹ̀kúnnù
Ègbè: Nǹkankan ò gbọdọ̀ ni wọ́n lára
Lílé: Ìyẹn ni gbogbo
Ègbè: Ọmọráyé fi ń ṣèdárò fún un
Lílé: Ìyẹn ni gbogbo
Ègbè: Ọmọráyé fi ń ṣèdárò fún un
Àlìájì Múrítàlábì

(Hárúnà Ìṣọ̀lá - *Late Gen. Muritala Muhammed*)

Nínú àyọlò òkè yìí, Hárúnà Ìṣọ̀lá tọ́ka sí àwọn bẹbẹ tí Ọ̀gágun Muritala Ramat Muhammed gbé ṣe nígbà tí ó jẹ́ olórí orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, kí ó tó di pé wọ́n pa á. Lára ohun tí ó ṣe ni pé ó mú gbogbo ohun tí ó le koko kí ó tó dé orí àlááfà rọ̀, kí ara lè tu àwọn mẹ̀kúnnù. Kò fẹ́ kí ara ni àwọn mẹ̀kúnnù rara. Ó hàn nínú orin òkè náà pé àwọn nǹkan tí ó gbé ṣe yìí gan-an ni ó jẹ́ kí àwọn ènìyàn máa ṣe ìdárò rẹ̀.

Àpẹẹrẹ mìíràn tún hàn níbi tí King Sunny Ade ti tọ́ka sí àwọn ohun ribiribi tí Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ ṣe nígbà tí ó wà ní ipò. Èyí hàn nínú àwọn àyọlò ìsàlẹ̀ yìí:

Lílé: Àjànàkú sùn bí òkè
Erin ṣubú kò mà lè dìde
Ègbè: Áàwolọ́wọ̀, ó di gbéré
À ń wá a, a ò rí i
A ò rójú onígbèjà mọ́

Ááwólọwọ̀, ó di gbéré
À ń wá a, a ò rí i
A ò rójú onígbèjà mọ́
Ááwolọwọ̀, ó di gbéré

Lílé: Àjànàkú kò ṣé fa nírù
Ègbè: Kó tó kú
Lílé: Olótìtọ́ ènìyàn kì í ṣọ̀rẹ́ aráyé
Ègbè: Ìgbà tó kú tán la wá mọyì Ọbáfẹ́mi
Awólọ́wọ̀ ṣerú dọmọ ọ
Awólọ́wọ̀ sọ wá doge o ò
Awólọ́wọ̀ ṣerú dọmọ ọ
Awólọ́wọ̀ sọ wá doge o ò
Ta ló le gbàgbé?
Ta ló le gbàgbé?
Ohun rere tÁwólọ́wọ̀ ṣe sílẹ̀ fún wa?

Lílé: Ìwòsàn ọ̀fẹ́ fún gbogbogbòò
Ètò ẹ̀kọ́-ọ̀fẹ́ fún gbogbo wa
Ẹ̀kúnwó òṣìṣẹ́ òun lẹni àkọ́kọ́ tó ṣe é
Ẹ̀rọ-amóhùn-máwòrán àkọ́kọ́ lÁfirikà
Ètò ilé olówó pọ́ọ́kú
Ẹ̀ka tó mójútó ààbò àwọn tí n rìnrìn-àjò
Títí lọ fi dé ilẹ̀-mímọ́
Liberty Stadium ní ká sọ ni
Tàbí ti Cocoa House tìlú Ìbàdàn?
Jagunlabí tún ṣere fálejò ó ṣe fónílé
Ègbè: Ó ṣe e!
Ó mà má ṣeun ò
Ọbáfẹ́mi ṣere fálejò ó ṣe fónílé kó tó lọ
(Sunny Ade - 'Late Papa Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ S.A.N.' nínú *Jealosy*)

Ó hàn nínú àwọn àyọlò orin òkè yìí pé iṣẹ́ tí Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ nígbà tí ó jẹ́ olóòtú ìjọba Ìwọ̀-Oòrùn kò kéré. Lára àwọn àwọn nǹkan náà ni pé ó jẹ́ olùgbèjà àwọn mẹ̀kúnnù, ó sọ ẹrú di ọmọ, ó jà fún òmìnira àwọn ènìyàn, ó ṣe ètò ìwòsàn ọ̀fẹ́, ẹ̀kọ́-ọ̀fẹ́ àti ẹ̀kúnwo owó-oṣù òṣìṣẹ́. Bákan náà, ó tún ilé-iṣẹ́ amóhùn-máwòrán àkọ́kọ́ ní ilẹ̀ Áfirikà sí ìlú Ìbàdàn, ó kọ àwọn ilé olowó pọ́ọ́kú fún àwọn mẹ̀kúnnù, ó mójú tó ètò ààbò ìlú, ọ́ kọ́ pápá ìṣeré *Liberty Stadium* àti *Cocoa House* sí ìlú Ìbàdàn, ó sì ṣe ètò ìjọba tí ó karí tẹrú-tọmọ. Gbogbo àwọn nǹkan wọ̀nyí fi hàn pé akọni ènìyàn tí ó ṣe bẹbẹ ní ipò ni òṣèlú ni Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀.

Àpẹẹrẹ mìíràn tún hàn nínú orin tí Odòlayé Arẹ̀mú ti tọ́ka sí ìfarajìn Ààrẹ Samuel Ládòkè Akíntọ́lá ṣe nígbà tí ó wà ní ipò ìṣàkóso ìjọba Ìwọ̀-Oòrùn. Èyí hàn nínú àyọlò ìsàlẹ̀ yìí:

Ọmọ-ọmọ kẹ́kẹ́yẹjú, ọmọ Abídogun
A bìdóni bí ìpìn baba Ìwàloyè!
Wàá bí ààrá sán, ọ̀gbaraga, bìtú yaǹya
Àjàlá-Àgbé tíí mọ́mọ láàsẹ̀jà sọnù
Kúrímọ̀dì ọmọ òpetu, kòkòkîì ọmọ ìsàlẹ̀ òjé

Àjàlá-Àgbé ń bẹ ní ọ̀run ọ̀sán gangan!
Kíyà ọ́ mọ́ jẹ Yóòbá ló fa sábàbí ẹ̀
(Odòlayé Àrẹ̀mú - *Ikú Akíntọ̀lá*)

Ó hàn nínú àyọlò orin òkè yìí pé Àarẹ Samuel Ládòkè Akíntọ̀lá ara rẹ̀ jìn ni nítorí kí ìyà má baà jẹ́ àwọn ìran Yorùbá. Èyí ni pé tí ó bá jẹ́ pé onímọ̀ tí ara-ẹni nìkan ni Àarẹ Samuel Ládòkè Akíntọ̀lá, ó ṣeé ṣe kí ó má kú irúfẹ́ ikú tí ó kú.

## Àgbálọgbábọ̀

Iṣẹ́ yìí ṣe àlàyé lórí pé àwọn akọni tí ó bá gbé ilé ayé ṣe rere kì í kú kúrò láyé tán nítorí bí wọ́n bá kú tán, orúkọ wọn kì í parẹ́ mọ́ nílé ayé. Irúfẹ́ àwọn akọni tí orúkọ wọn ò parẹ́ lẹ́yìn ikú wọn ni ó pè ní akọni gbére. Èyí tí ó túmọ̀ sí àwọn akọni tí wọn yóó máa jẹ́ akọni títí ayé. Iṣẹ́ yìí fi hàn pé orin kíkọ ní àwùjọ Yorùbá jẹ́ ọ̀nà kan láti de àwọn akọni gbére mọ́lẹ̀ nítorí pé àwọn akọrin máa ń fi wọ́n ṣe orin kọ. Ó tún hàn nínú iṣẹ́ yìí pé ó ní àwọn kókó-èrò tí àwọn ọ̀kọrin máa ń fi hàn nípa àwọn akọni gbére. Lára àwọn kókó-èrò bẹ́ẹ̀ tí iṣẹ́ yìí tọ́ka sí ni ìdárò ikú akọni, ìtọ́kasí irúfẹ́ ikú tí ó pa wọ́n, ìtọ̀kásí ẹni tí ó kú gẹ́gẹ́ bí ènìyàn ńlá, ipò tí òkú dì mú nígbà tí ó wà láyé àti bẹbẹ tí ó gbé ṣe lórí ipò náà.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Adémúyìwá, A.L. (2017). "Ìtúpalẹ̀ Ìmọ̀ Ìṣọwọ́lò-Èdè nínú Àsàyàn Ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù". Unpublished M.A Thesis, Department of Linguistics and African Languages, Ọbáfẹ́mi Awólówọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Adéoyè, C. L. (1980) *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá*. Ibadan: University Press Ltd.

Akínwùmí, P.A. (2015). "Àgbéyẹ̀wò Àwọn Kókó Ọ̀rọ̀ Àti Ìṣọwọ́-lò-Èdè nínú Orin Ṣẹ́gun Akinlolú". Unpublished M.A Thesis, Department of Linguistics and African Languages, Ọbáfẹ́mi Awólówọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Akínwùmí, P.A. (2023). "Yorùbá Poetry: An Elixir of the Nigeria National Security and Integration. Ifẹ̀ Journal of Languages, Literature and Linguistics (IJLLL): A Journal of the Department of Linguistics and African Languages, Ọbáfẹ́mi Awólówọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀. Nigeria. Vol 9 (1), 1-26.

Ajíbádé, G. O. (2007). "New Wine in Old Cups: Postcolonial Performance of Christian Music in Yoruba Land". *Studies in World Christianity.* Pp105-126.

Ajíbádé, G. O. (2010). "The Hunting Poem: A psychoanalysis of Contemporary Yorùbá Elegy(Orin Òkú Ọ̀fọ̀)". In Bọ́dúndé, C. (ed) *Text and Theories in Transition: Black African Literature and Imagined Tradition*. Bayreuth African Studies 89. Pp 76-90.

Ajíbádé, G. O. (2020). "A Sociocultural Appraisal of Yoruba Kegites songs". *Yoruba Studies Review.* Vol 5, no 1,2. Pp39-52.

Àjùwọ̀n, B. (1981). *Ìrèmọ̀jé Eré Ìṣípà Ọdẹ*. Ìbàdàn: University Press Ltd.

Àjùwọ̀n, J. (2017). "Ìtúpalẹ̀ Àṣàyàn Oríkì àwọn Akọnikùnrin àti Akọnibìnrin Yorùbá ní Ìwọ̀Oòrùn Gúúsù Orílẹ̀-Èdè Nàìjíríà". Unpublished PhD. Thesis submitted to the of Department of Linguistics and African Languages, Obafemi Awolowo University, Ile-Ife.

Ali, S. H. (1982). Murtala Muhammed: A betrayed revolutionary. Publicity Communications.

Àmàó, T. A. (1988). *Àròfọ̀ Òkú Pípè*. Ikeja: Longman Nigeria.

Carte, D. T. (2026). Harmonizing literary criticism: How AI can help resurrect the author and unite the banners of literary theory. Literature, 6(1), 3.

Editorial Board. (2025, July 25). Ọba Síkírù Adétọ̀nà (1934-2025). *The Guardian Nigeria News*. http://guardian.com

Gallagher, C., àti Greenblatt, S. (2000). Practicing New Historicism. University of Chicago Press.

Garba, J. N. (1982). Revolution in Nigeria: Another chance. African Publishers.

Hassan, J. (2025, July 13). Awujale of Ijebuland, Adetọna, dies at 91. *Punch Newspapers*, http://punching.com

Levine, R. S. (2022). "That Grim Sphinx": Literary historicism and Tourgée's Toinette novels. American Literary History, 34(1), 224–236.

Ogunsanwo, G. (1976, Feb 25). Sunday Times, February 13, 1976.

Olajide, A. (2020). Why Muritala Mohammed was assasinated. Caltop Publications.

Oyediran, O. (Ed.). (1979). Nigerian government and politics under military rule, 1966-1979. Macmillan.

Panter-Brick, K. (Ed.). (1978). Soldiers and oil: The political transformation of Nigeria. Frank Cass.

Shittu, T., àti Ayinla, S. (2022). A New Historicist reading of Wole Soyinka's The Strong Breed and Femi Osofisan's No More the Wasted Breed. Isagoge: Journal of Humanities and Social Sciences, 2(8).

Siollun, M. (2009). Oil, politics and violence: Nigeria's military coup culture (1961–1976). Algora Publishing.

The Guardian, July 13, 2025 www.guardian.ng/news/awujale-of-ijebu-oba-adetona-dies-at-91

Zhuravleva, O. A. (2022). Historicism as an aspect of novel thinking. Semiotic Studies, 2(4), 53–58.

## Àkójọ Àwọn Orin

Adegeye, S. A. (1987). *Late Papa Obafemi Awolowo S.A.N, G.C.F.R.* (*Song*). *On Jealosy (Album)*. Atom Park Ltd, Vol. 24

Ayinde, S. O. (1993). *Late Alhaja Simbiat Atinuke Abiola (Song). On Fuji Dimension (Album)*. Barry Black Music, Vol. 49

Hárúnà, I. B. (1955). *Late Ọba Adeboye -The Orimolusi Of Ijẹbu Igbo (Song). On Late Oba Adeboye -The Orimolusi of Ijebu Igbo (Album).* Star Records, SRPS, Vol. 49

Hárúnà, I. B. (1976). *Late Gen. Muritala Muhammed (Song). On Late Gen. Muritala Muhammed -The Orimolusi of Ijebu Igbo (Album).* Star Records, SRPS, Vol. 31

Obey-Fabiyi, E. (2025). *Late Ọba Síkírù Káyọ̀dé Adétọ̀nà (Live Recording)*. Awujale Street, Ijebu-Ode, Nigeria. YouTube. *Ebenezer Obey YouTube.Song Town 26 Jul 2025.*

Odòlayé, A. (1978). Ikú Akíntọ́lá *(Song). On Ikú Akíntọ́lá (Album).* Olatubosun Records Company, ORCLP, Vol. 23.

## Author's Bio

**Dr. Paul Akintunde Akinwumi** Ph.D, is a Lecturer in the Department of Linguistics and African Languages, Obafemi Awolowo University, Ile-Ife. Nigeria. He got his B.A. and M.A. in Yorùbá Language and Literature from the Obafemi Awolowo University, Ile-Ife. He further to have his Ph.D in Yorùbá Literature from the Obafemi Awolowo University, Ile-Ife. Nigeria. He was the first recipient of Chief Alex Akinyele Prize, for the best male graduating student in the Faculty of Arts, Obafemi Awolowo University, Ile-Ife, Nigeria in year 2004. He also won Professor Wande Abimbola Prize, for the student with the best overall performance in the B.A. Yoruba Examination, 2004. He has received a number of commendations from the University managements for invaluable services rendered in the maintenance of peace, safety and notable participation in the developmental activities on the university community. His areas of research interests are Yoruba literature, culture and performance. He also explores studies on religion and society, security, environment and gender studies.He has done extensive study on Yorùbá poetry, culture and gender; the outcome of the studies culminated in the completion of a doctoral dissertation and a number of publications.

Recebido em: 03/2026

Aceito em: 30/07/2026

**Para citar este texto (ABNT):** AKINWUMI, Paul Akintunde. Èrò nípa Akọni Gbére Ajẹmóṣèlú nínú Orin Ìdárò Yorùbá. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), vol.6, nº Especial III, p.247-263, agosto 2026.

**To cite this text (APA):** Akinwumi, Paul Akintunde (august 2026). Èrò nípa Akọni Gbére Ajẹmóṣèlú nínú Orin Ìdárò Yorùbá. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 6 (Special III): 247-263.